# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KỌKÀNLÁ, ỌDÚN 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KỌKÀNLÁ 2021 – DÍDÒJÚKỌ ÌRÚNÚ ÀWỌN Ẹ̀MÍ JẸRAN-JẸRAN ÀTI MÙJẸ̀-MÙJẸ̀ (2)

7:00 am – 7:05 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀
7:05 am – 7:20am Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn
7:20 am – 7:35 am Ijẹ́rì
7:35 am – 7:45 am Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdáṣe
7:45 a m – 8:45 am Iṣẹ́ Ìránṣẹ́
8:45 am - 9:00 am Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

**Orin ibẹ̀rẹ̀**

1. " Wọ ha nfẹ́ bọ́ lọ́w'ẹru ẹṣẹ rẹ̀?
   Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Rẹ;
   'Wọ̀ ha fẹ gba'ṣẹ́gun lóri eṣù?
   Agbára mbẹ n'nú ẹ̀jẹ̀ Rẹ.

   Ègbè: Agbára ..........nlá..........
   Tí nṣiṣẹ́'yànu
   Mbẹ nínú..........ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀..........
   Agbára..........nlá...................
   Tí nṣiṣẹ́'yànu
   Ó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù

2. "Wọ ha nfẹ́ bọ́ l'ọw'agbára ẹ̀ṣẹ̀?
   Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Rẹ
   Wá fún iwẹ̀nùmọ́ ní Kálfárì
   Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Rẹ

   Ègbè: Agbára ..........nlá..........
   Tí nṣiṣẹ́'yànu
   Mbẹ nínú..........ẹ̀jẹ̀ Rẹ..........
   Agbára..........nlá...................
   Tí nṣiṣẹ́'yànu

Ó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù

3. Wọ ha nfẹ kí ọkàn rẹ funfun láú?
   Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Rẹ
   Ẹ̀jẹ̀ Rẹ ló nwẹ abàwọ́n ẹ̀ṣẹ
   Agbára mbẹ n'nú ẹ̀jẹ̀ Rẹ

   Ѐgbè: Agbára ..........nlá..........
   Tí nṣiṣẹ́'yànu
   Mbẹ nínú..........ẹ̀jẹ̀ Rẹ..........
   Agbára..........nlá...................
   Tí nṣiṣẹ́'yànu
   Ó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù

4. Wọ ha nfẹ ṣiṣẹ́ fún Olúwa Rẹ
   Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Rẹ
   'Wọ ha nfẹ fi gbogbo ayé rẹ yin?
   Agbára mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀

   Ѐgbè: Agbára ..........nlá..........
   Tí nṣiṣẹ́'yànu
   Mbẹ nínú..........ẹ̀jẹ̀ Rẹ..........
   Agbára..........nlá...................
   Tí nṣiṣẹ́'yànu

Ó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Baba mi, jẹ ki imọlẹ Rẹ tan sori okunkun aye mi lonii, ní orúkọ Jésù.
2. Baba mi, bẹ mi wo, ki O si le gbogbo okunkun kuro ninu aye, ile ati iṣẹ mi, ní orúkọ Jésù.

3. Agbárákagbara tó sọ ara rẹ dí okùnkùn fún ayé mi, dìde Olúwa, fọ́ ọ̀pa ẹ̀yìn rẹ lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ogun okùnkùn, tó n lo ọgànjọ́ òru láti pọ́n ayé mi lójú, àrá Ọlọ́run yóò pa ọ́ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá mi, jẹ́ kí àwọn alùmọ́nì ọ̀run kórajọ láti rànmí lọ́wọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ẹrù ibi tí wọ́n gbé lémi lórí, tó n ba àwọn ohun rere jẹ́ nínú ayànmọ́ mi, iná Ọlọ́run yóò dáná sun ọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ẹrù ibi ilé bàbá mi tí wọ́n gbé lémi lórí, Olúwa, jẹ́ kí iná Rẹ gbá wọn dànù lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára òkùnkùn yówù tó dáná láti jó èmi àti àwọn ọmọ mi, iná rẹ yóò dà lé ọ lórí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára tó n fi'ṣẹ́ ọwọ́ mi pọ́n mi lójú, túmi sílẹ nípa iná, ki o sì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Aìlèra tí ọ̀tá n lò láti fi bámi jà, fí ayé mi silẹ̀, ki o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, bá aìlèra tó n jọba nínú ayé mi wí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ékún nínú ayé mi, tí ayé tí tọwọ́bọ̀, tó n dí mi lọ́wọ́ kí n má lè ráyè wọnú ogún ìbí mi lọ, gba okun, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**2 Tímótéù 1:7:** Nítorípé Ọlọ́run kò fún wa ní ẹ̀mí ìbẹ̀rù; bíkòṣe ti agbára, àti ti ìfẹ́, àti ti ọkàn tí ó yè koro.

**Isàíàh 40:29:** Ó nfi agbára fún alárẹ̀; o sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá.

**2 Kọ́ríntì 10:3-5:** Nítorípé bí àwa tilẹ̀ nrìn ní ti ara, ṣùgbọn àwa kò jagun nípa ti ara: (Nítorí ohun ìjà wa kì íṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó lí agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;) Àwa nsọ gbogbo èrò kalẹ̀, àti gbogbo ohun gíga tí ngbé ara rẹ ga sí ìmọ̀ Ọlọ́run, àwa sì ndi gbogbo èrò ní ìgbèkùn wá sí ìtẹ́ríba fún Krístì;

**Orin Dáfídì 6:2:** Olúwa, ṣànú fún mi; nítorí aìlera mi: Olúwa, mú mi lára dá; nítorí tí ara kan egungun mi.

**Orin Dáfídì 30:2:** Olúwa Ọlọ́run mi, èmi kígbe pè ọ, ìwọ si ti mú mi lára dá.

**Iṣé Àwọn Apóstéli 1:8:** Ṣùgbọ́n ẹ̀nyin ó gba agbára, nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bá bá lè nyín: ẹ ó sì má ṣe ẹlẹ́rì mí ní Jerúsálémù, àti ní gbogbo Jùdéà, àti ní Samáríà, àti títí dé òpin ilẹ̀ ayé.

**Lúkù 24:49:** Sì kíyèsì i, Mo rán ileri Bàbá mí sí nyín: ṣùgbọ́n ẹ jókò ní ìlú Jerúsálémù, títí a ó fí fì agbára wọ̀ nyín, láti òkè ọ̀run wá.

**Orin Dáfídì 62:11:** Ọlọ́run ti sọ̀rọ̀ lẹ́kàn; lẹ́rìnkejì ni mo gbọ́ èyí pé: ti Ọlọ́run li agbára.

**Orin Dáfídì 89: 13:** Ìwọ ni apá agbára: agbára li ọwọ́ rẹ, gíga li ọwọ́ ọ̀tún rẹ.

## <u>ÌJẸ́WỌ́ ÀTI ÀDÚRÀ SÓRÍ ÀWỌN OHUN ÈLÒ IRINṢẸ́</u>

Bàbá, mo fi ohun èlò irinṣẹ́/iṣẹ́/òwò mi sí Ọwọ́ mímọ́ Rẹ. Ati kọ́ ọ́ pé, nítorí èmi mọ ẹnití èmi gbàgbọ́, ó sì dá mí lójú pé, òn lè pa ohun tí mo fi lé e lọ́wọ́ mọ́ títí di ọjọ́ nì (2 Tímótéù 1:12).
Bàbá, jẹ́ kí àwọn ohun èlò irinṣẹ́/iṣẹ́/òwò yìí di ààké ogun tí yóò mú ayé mi tẹsìwájú lọ́nà ọ̀tun, ní orúkọ Jésù.
Agbára ájìnde, agbára imúpadàbọ̀ sípò, agbára ojúrere atòkèwa, agbára iṣèrere, agbára alàjá, agbára itàyọ, bàlé ohun elo iṣẹ́ mi, ní orúkọ Jésù.

Nípa irinṣẹ́ mi yìí, jẹ́ kí n ni ìrírí àwọn ẹ̀rí tó nfa àwọ̀n ya. Jẹ́ kí n ní ìrírí alàjá tíkò wọ́pọ̀. Jẹ́ kì n ní ìrírí agbègbè tó gbóòrò. Jẹ́ kí n ní ìrírí ìlọsíwájú  atòkèwa, ní orúkọ Jésù.
Mo ri àwọn ohun èlò irinṣẹ́ mi àti ti owó mi sínú ẹ̀jẹ̀ Jésù. Mo ri i wọn sábẹ́ àtíbàbà iná Ọlọ́run Èlíjàh. Láti ìsisìyí lọ, jẹ́ kí ohun èlò irinṣẹ́ mi bẹ̀rẹ̀ siní mú ọ̀pọ̀ èrè tíkò wọ́pọ̀, àwọn ẹ̀ri tíkò wọ́pọ̀ àti alàjá tíkò wọ́pọ̀ wà, ní orúkọ Jésù.

1. Bàbá Olúwa, jẹ́ kí gbogbo irúgbìn sátánì di fífọ̀ jáde kúrò nínú òwò/iṣẹ́ mi, ní orúkọ Jésù.
2. Olúwa, jẹ́ kí àwọn ọwọ́ àti ẹsẹ̀ àjèjì tó n dí ìṣerere iṣẹ́ ọwọ́ mi lọ́wọ́ gbi’ná, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá mi, jẹ́ kí ẹ̀mi ojúrére baptísì òwò/iṣẹ́ mi fún iṣérere tíkò làmì laka, ní orúkọ Jésù.
4. Iwọ́ ohun èlò irinṣẹ́ mi, di ibùkún, kì í íṣe ègún, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, fọ gbogbo ìdin, àkekè àti ejò kúrò nínú ohun èlò irinṣẹ́ mi, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ègún tí wọ́n fi sórí ìṣerere iṣẹ́ ọwọ́ mi, fọ́ nípa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù.
7. Bàbá, jẹ́ kí ọrọ̀ àwọn aláìwà-bí-Ọlọ́run ní agbègbè mi, sípò padà sọ́wọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
8. Darí mi, Olúwa, lọ síbi ilẹ̀ mi tó n ṣàn fún wàrà àti oyin, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí onfà ìṣerere atòkèwá di gbígbìn sínú àwọn ọwọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
10. Mo gba àpamọ́wọ́ mi kúrò lọ́wọ́ Júdásì ìdílé bàbá mi, ní orúkọ Jésù.
11. Mo gba atúkọ̀ ọrọ̀ mi kúrò lọ́wọ́ àwọn awakọ̀ ibi, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí agbára pàrọ̀ ọwọ́ nínú òwò/iṣẹ́ mi, fún ọ̀run tó ṣí sílẹ̀ lórí àwọn ètò ìṣúná mi, ní orúkọ Jésù.
13. Ẹ̀mí Mímọ́, darí ọwọ́ mi sínú ìṣerere, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo ìbọ̀dè lòrì iṣẹ́ ọ̀wọ̀ mi, túká nípa iná, ní orúkọ Jésù.